# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OṢÙ KỌKÀNLÁ, ỌDÚN 2022**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**ÌTÚSÍLẸ̀ ÌDÍLÉ (2)**

## OṢÙ KỌKÀNLÁ, ỌDÚN 2022 - ÌTÚSÍLẸ̀ ÌDÍLÉ (2)

| | |
|---|---|
| 7:00 am – 7:05 am | Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀ |
| 7:05 am – 7:20am | Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn |
| 7:20 am – 7:35 am | Ijẹ́rì |
| 7:35 am – 7:45 am | Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdágbà |
| 7:45 a m – 8:45 am | Iṣẹ́ Ìránṣẹ́ |
| 8:45 am - 9:00 am | Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé |

## Ẹ SIN OLÚWA

1. Ẹ sin Olúwa nínú ẹwà ìwà mímọ́!
Wólẹ̀ fún k'ẹ sì pókìkí 'ògo Rẹ̀;
Pẹ̀lú wúrà 'gbọ́ràn àti turàrí 'rẹ̀lẹ̀,
Ẹ wólẹ̀ fún Un: k'ẹ sì júbà Rẹ.

2. Gbé ẹ̀rù àníyàn yín lé'lẹ̀ l'ẹ́sẹ̀ Rẹ:
Y'ó sì tì ka Rẹ̀ bá yin gbe d'órí;
Y'ó tù ọ́ nínú, yó sì gbọ́ àdúrà rẹ,
Y'ó tọ̀ ṣíṣẹ̀ rẹ bó ti tọ́ fún ọ.

3. Má bẹ́rù láti wọ agbàlá Rẹ̀ pẹ̀lú,
Kíún nínú ọ̀rọ̀ t'ó lé pè n'tirẹ̀:
Ẹ̀wà òtítọ́ àti ìfẹ́ òwúrọ̀,
Ẹbọ wọ́nyì là nbèrè lọ́wọ́ rẹ.

4. B'a tilẹ̀ m'áwọn wọ̀nyí wà ní 'wárírì,
Òn y'ó gbáwọn l'órúkọ tó ṣọ́wọ̀n,
Ayọ̀ òwúrọ̀ y'ó dípò ẹkún alẹ́,

Irètí kíkún y’ó dípò ẹrù.

**ÓSÙN N’SÀ ÒKÚ OLÙGBÀLÀ MI**

1. Ósùn n’sà òkú Olùgbàlà mi,
   N’dúró d’ọjọ́ tí mbọ̀ Olúwa mi!

   Ní’bòji l’ójí dìde;
   Pẹ̀lú sẹ́gun lórí ọ̀tá rẹ;
   Ò jíndè pẹ̀lú ‘sẹ́gun lór’ókúnkùn,
   Ó jọba tití pẹ̀l’áwọn ẹni mímọ́.
   Ójìnde.............Ójìnde
   Allélúyàh! Krístì jíndè!

2. Lásán l’asọ́ bòji, Olùgbàlà mí,
   Lásán lay’ókùta dí bojì!

   Ní’bòji l’ójí dìde;
   Pẹ̀lú sẹ́gun lórí ọ̀tá rẹ;
   Ò jíndè pẹ̀lú ‘sẹ́gun lór’ókúnkùn,
   Ó jọba tití pẹ̀l’áwọn ẹni mímọ́.
   Ójìnde.............Ójìnde
   Allélúyàh! Krístì jíndè!

3. Ikú kòlè borí Olùgbàlà mí;
   Ójá gbogbo ìdè, Olúwa mi!

   Ní’bòji l’ójí dìde;

Pẹ̀lú sẹ́gun lórí ọ̀tá rẹ;
Ò jíndè pẹ̀lú 'sẹ́gun lór'ókúnkùn,
Ó jọba títí pẹ̀l'áwọn ẹni mímọ́.
Ójìnde.............Ójìnde
Allélúyàh! Krístì jíndè!

## **Ọ̀RỌ̀ AGBÁRA**

1. Lónì, mo de ayànmọ́ mi mọ́ orísun ojúrere atòkèwá, nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù. Gbogbo ilẹ̀kùn rere tó tì lòdì sí ayànmọ́ mi rí yóò ṣí nípa iná lónì, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo agbára òkùnkùn, tí wọ́n yàn láti ṣàtúntò ayànmọ́ mi, lónì, Ọlọ́run Èlíjàh t'Ó n finá dáhùn yóò pa ọ́ run, ní orúkọ Jésù.
3. Nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, lónì, àwọn àngẹ̀lí ìparun yóò bẹ àgọ́ àwọn ọ̀tá mi olóríkunkun wò, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run dìde, jẹ́kí gbogbo ìgbámú ìmísí sàtánì, lórí ìdílé mi fọ́ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo májẹ̀mú òṣì àti ìpọ́njú nínú ìran mi, nípa dídá orúkọ Jésù, wọn yóò fọ́ ọ́ lónì, ní orúkọ Jésù.
6. Ọ̀rọ̀ Olúwa tí yóò tọ̀ mí wá lónì yóò rómilágbára láti tún ìtàn ìdílé mi kọ, ní orúkọ Jésù.
7. Ìdílé mi, ìdílé mi, ìdílé mi, gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa; gba okun àti agbára láti ṣerere, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo ohùn òṣì lórí ìdílé mi, gba ìpalẹ́numọ́ títí láí, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo ọfà òṣì tó n fò lágbégbè mi, mo kọ̀ láti jẹ́ ìjẹ rẹ, padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
5. Mo fọ́ gbogbo ègún òṣì tí wọ́n fi sórí ìran mi, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo májẹ̀mú òṣì, tí wọ́n bá omi àti ilẹ̀ agbègbè mi dá, fọ́ lórí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run, múmi ṣerere ní ilẹ̀ yìí, kí O sì jẹ́kí n di alábùkúnfún, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ ỌRỌ̀ NÁÀ

**2 Tímótéù 1:7:** Nítorípé Ọlọ́run kò fún wa ní ẹ̀mi ìbẹ̀rù; bíkòṣe ti agbára, àti ti ìfẹ́, àti ti ọkàn tí ó yè koro.

**Isàíàh 40:29:** Ó nfi agbára fún alárẹ̀; ó sì fi agbára kún àwọn tí kò ní ipá.

**2 Kọ́ríntì 10:3-5:** Nítorípé bí àwa tilẹ̀ nrìn ní ti ara, ṣùgbọ́n àwa kò jagun nípa ti ara: (Nítorí ohun ìjà wa kì íṣe ti ara, ṣùgbọ́n ó lí agbára nínú Ọlọ́run láti wó ibi gíga palẹ̀;) Àwa msọ gbogbo èrò kalẹ̀, àti gbogbo ohun gíga tí ngbé ara rẹ̀ ga sí ìmọ̀ Ọlọ́run, àwa sì ndi gbogbo èrò ní ìgbèkùn wá sí ìtẹ́ríba fún Krístì;

**Orin Dáfídì 6:2:** Olúwa, ṣànú fún mi; nítorí àìlera mi: Olúwa, mú mi lára dá; nítorí tí ara kan egungun mi.

**Orin Dáfídì 30:2:** Olúwa Ọlọ́run mi, èmi kígbe pè ọ́, ìwọ sì tì mú mi lára dá.

**Ìṣe Àwọn Àpóstélì 1:8:** Ṣùgbọ́n ẹ̀nyin ó gba agbára, nígbàtí Ẹ̀mí Mímọ́ bà lé nyín: ẹ ó sì ma ṣe ẹlẹ́rì mi ní Jerúsálémù, àti ní gbogbo Jùdéà, àti ní Samáríà, àti títí dé òpin ilẹ̀ ayé.

**Lúkù 24:49:** Sì kíyèsí í, Mo rán ìlérí Bàbá mi sí nyin: ṣùgbọ́n ẹ jókò ní ìlú Jerúsálémù, títí a ó fi fi agbára wọ̀ nyín, láti òkè ọ̀run wá.

**Orin Dáfídì 62:11:** Fún wa ní ìrànlọ́wọ́ nínú ìpọ́njú: nítorí pé asán ni ìrànlọ́wọ́ ènìyàn.

**Orin Dáfídì 89:13:** Ìwọ ni apá agbára: agbára li ọwọ́ Rẹ, gíga li ọwọ́ ọ̀tún Rẹ.

## <u>ÀDÚRÀ FÚN ÌTÚSÍLẸ̀ ÌDÍLÉ</u>

1. Gbogbo ìlànà òdì, àmúyẹ òdì, ìṣe òdì àti ìwà búburú tó n ṣàn látorí igi ìdílé mi, mo mú ọ so nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
2. Ìwọ ẹ̀mí òkùnkùn tó díjú àti ìfinijì ìgbà láíláí, tó n yọ ìran mi lẹ́nu, pòórá, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo ẹranko sátánì, tó n gbé nínú igi ìdílé mi, gbaná, kosì kú, ní orúkọ Jésù.
4. Ọfà amúbina ìkà, tí wọ́n dojú rẹ kọ ìran mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
5. Ìwọ ọ̀run lórí iṣèrere ìdílé mi, ṣí nípa iná, ní orúkọ Jésù.
6. Mo kọ̀ láti jẹ́ itẹ̀sìwájú ikùnà-kíkùnà ilé bàbá mi, ní orúkọ Jésù.

7. Àìṣedéde tó gbé àwọn òbí mi mìn, kòní gbé mi mìn, ní orúkọ Jésù.
8. Gbogbo ẹ̀mí agbègbè, tí wọ́n yàn lòdì sí ìdílé mi, gba ìmúso, ní orúkọ Jésù.
9. Olúwa, jẹ́ kí àrá àti iná pa gbogbo ẹ̀rọ ìtọpinpin sátánì, tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ìdílé mi, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo ààlè sátánì, tí wọ́n fi sórí ìran mi,gba ìparun nípa iná, ní orúkọ Jésù.
11. Gbogbo agbára tó n bá àwọn ètò Ọlọ́run jẹ́ fún ìdílé mi, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
12. Ọ̀rọ̀ ìyówù tí wọ́n sọ sínú òòrùn àti oṣùpá lòdì sí ìran mi, gba ìparun nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
13. Gbogbo agbára, tó n fa agbára láti inú ọ̀run lòdì sí ìdílé mi, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
14. Mo gé orí Golìátì ìran mi ṣọnù, ní orúkọ Jésù.
15. Gbogbo ọ̀rẹ́ òkùnkùn nínú ìran mi, kí àṣírí yín tú, kẹsì gba ìtìjú, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo ègún tó n tako iṣèrere, tó n ṣàn láti orí igi ìdílé mi, fọ́ nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo ẹ̀mí ìbíntín, tó n ṣàn láti orí igi ìdílé mi, kú, ní orúkọ Jésù.
18. Gbogbo ìṣúná tó ti yarọ, tó n ṣàn láti orí igi ìdílé mi, kú, ní orúkọ Jésù.
19. Gbogbo ègún ikú àìtọ́jọ́, tó n ṣàn láti orí igi ìdílé mi, fọ́ nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
20. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, fọ èérí kúrò nínú ìran ẹ̀jẹ̀ mi, ní orúkọ Jésù.
21. Ìwọ ọkùnrin alágbára tó n ṣabòjútó àwọn iṣẹ́-lábi ègbé lórí igi ìdílé mi, ṣubú sínú erùpẹ̀, kosì di àgbégbìn, ní orúkọ Jésù.